“Ọlọhun ti O lágbára ti O gbọnngbọn ko nii ṣàánú ẹni tí kii ba ṣàánú àwọn èèyàn”

Láti ọdọ Jariir ọmọ Abdullahi- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Òjíṣẹ́ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ọlọhun ti O lágbára ti O gbọnngbọn ko nii ṣàánú ẹni tí kii ba ṣàánú àwọn èèyàn”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n ṣàlàyé pe ẹni ti kii ba ṣàánú àwọn èèyàn, Ọlọhun ko nii ṣàánú rẹ, aanu ẹrú fún èdá Ọlọhun jẹ ọkan ninu awọn okùnfà ti o tobi ju lati ri aanu Ọlọhun ti ọla Rẹ ga gbà.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5439